ASAYAN ORO

**Arin irin gbęrę ni yio mu oye dele, asure tete ko ni ri oye ję. Gbogbon kan ko si, a fi ęniti o ba nti ara rę.**

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

Akiyesi Pataki

A fiwe yi şe ikede si awon Aşoju iwe iroh Eleti Ofe k kiri agbaiye wipe, enkeni ti ko ba f owo ti o fi je ranse si wa, a o pe lejo, ako si ni f i iwe iroh in ransę si enibe mo.

VOL. XI No. 636. LAGOS, SATURDAY, AUGUST 8 AUGUST 14, 1959. KǪBǪ MEJI (2d)

# Igbimo Nla Ti Ijoba Apapose (House Of Rep:) Bere Ipade Igbehin.

**EKO. Ipade ikęhin ti ile Igbimǫ nla ti apapǫşe (House of Representatives) ti ilu Eko bęrę ni ǫjǫ Alaruba (Wednesday) ti işe ǫjǫ karun oşu August 1959, ki a to tu ile igbimǫ na ka fun eto ati yan awǫn enia ti yio mu opo ijǫba tabi awǫn olutǫkǫ ijǫba ominira ilę Nigeria ti ao gba lǫdun ti o mbǫ lagbara Edumare.**

**Dię ninu awǫn ofin titun ati awǫn atunşe ti nwǫn fę şe ninu ipade yi ni ofin Igbimǫ ibilę tilu Eko, (Lagos Town Council) nipa yiyan Ǫba ati awǫn Ijoye ilu Eko,** owo ti ijǫba yio na lori kikǫ Iga Idunganran ile ǫba Eko, ninu ofin na ni owo ti ǫba Eko yio ma gba laiko ni si labę ayęwo igbimo ibilę.

Lehinti nwon ba pari ipade igbimǫ ti igbehin ti nwon bere yi tan ni ao şe eto lati yan awon enia pataki ti yio ję olutǫkǫ ijǫba ominira tilę Nigeria.

**Ipade yi ni a le pe ni "Ajalǫ arungbe, ti ko ba mu onibode yio mu ero oko". Gbogbo nkan pataki ti nwon ba şe ninu ipade na ni ao fun ęnyin ǫkawe wa ni' dodo re ję.**

## Ijoba Gesi Fi Oko Ogun Ta Nigeria Lore




Awǫn ti a nwo aworan wǫn ninu ǫkǫ Ogun "Nigeria" yi ni Asoju Ijǫba Nigeria ati Ivafin

Omidan Oyinkan Abayomi pelu Oga Oko Ogun, Admiral Sir Manley Power, nigbati o nfi oko ogun na le Nigeria lowo.

Nibi awuyewuye na ni Aşoju ile Nigeria ti so wipe Alayeluwa Ǫba obinrin ti fi imuore re gba wipe ki a ma pe awǫn Ǫmo Ogun oju omi tile Nigeria ni "Royal Nigerian Navy"
Adupę fun Ijoba Gesi

### ALAYE NIPA ORO ǪLǪMǪGE PEDRO

**Awǫn ęgbę Alanu (British Red Cross Society) sipaya ohun ti o mbę nidi orǫ olomoge kan ti a npe ni Pedro ti o fę lo si le Kanada, o ti gba iwe oti şe gbogbo eto pari ki nwǫn to sǫ fun pe ko ni lǫ mo A gbo pe inu Ǫlomoge na baję tobę ti a gbo pe, o lanu o nwi bayi pe, k'ni mo şe kę?.**

Awǫn ęgbę Alanu şipaya oro wipe:- Ǫkan ninu awǫn ofin ti o wa fun enia ti o ba fe lo si Kanada ni wipe nwǫn ko gbodǫ dagba ju ǫmǫ odun medogun si mǫkandilogun lo, gbogbo awǫn tǫ fę lo silo Kanada ni a fi ofin yi şe daradara.

Omidan Pedro sǫ ninu iwe rę, ti o kǫ wipe a bi on ni ǫjǫ 26th oşu August 1940 o si sǫ fun enito gba iwe fun pe ninu oşu August ti a wa yi ni on yio di ǫmǫ ǫdun mǫkandilogun.

Şugbon nigbati Pedro lo mu iwe ǫjǫ ibi rę wa, lati fi gbawe aşę irin ajo, (Passport) nigbana ni a ri pe Omidan Pedro di omo odun merindinlogbon. Ko si nşe on nikan ni nwon şe be fun gbogbo awon ti ǫjǫ ori wǫn koja ǫdun mokandilogun ni a da pada sehin

# Ojo Isodi Ominira Fun Ile Malaya



Eniti a nwo ti o fi ida owo re te ile bi opa, ti o duro lori aropodogiri ti a nwo ninu aworan yi ni Thomas Nelson ti o wa niwaju ile Asoju ile Malaya ni gbangba ita Trafalgar nigboro ilu London, ati asia isodi ominira ile Malaya.

Lojo ti nwon ta asia yi nilu London, ojo na ni nwon gba ominira ni ile Malaya. Eniti o je asiwaju awon oselu ni Malaya ni Tunku Abdu Rahaman.

Latigba ti asi ti nse isin wa, a ko ye kuro ni Ita Onimalu. Nitorina ase ti Oba pa yi lodi si ase ti Ajele pa fun wa. A gbo wipe awon Serafu si mbe ni Onimalu na titi di isisiyi.

## ILEGBONA BE SILE NI OKE OYA

KADUNA. A gbo irohin lati ile Hausa wa wipe ijafara lewu arun sopnna ati arun lorun-lorun be sile ni Oke-Oya.

Ni agbegbe Kano ati Sokoto ni arun na koko be sile nibiti o gbe kolu awon enia merin. Sugbon l'agbegbe ile Kabba enia marun ni arun na mba ja.

(E. D.) a fi eyi ke si enyin ara isale Odo-Oya ti o ba fe lo sile Hausa, ki e duro ko nomba ki e to lo. Nitoripe ogun agbo tele ko npa oro.

# Kere O! Ijoba Ti Ona Ijebu

Ijoba se ikede wipe ki gbogbo awon moto ti o ba fe lo si Ibadan lati Eko ma gba ona Abeokuta.

Nitoripe ona ti a ngba lona Ijebu ti baje a si ntun se lowo apa ibiti o baje lona Titi Ijebu ni Buso kejilelogoji (Trunk Road 1) ni eti Shagamu l'agbegbe ile Remo.

Nwon fe tun Kerewi to mbe leti Sagamu se, eyiti moto kan baje ni odun ti o koja lo. Atunse na yio bere ni ojo isimi 16th osu August 1959, lati agogo mefa owuro.

Nitorina ki gbogbo awon moto ti o ba nlo si Ibadan, ki o gba ona Abeokuta.

## AWON KURUMO NFE MA PA EJA FUN ARA EKO

EKO. Irohin ti a tun ri gbo ni wipe, awon Kurumo ti o nse ise agbe tunbo npo si nileyi, awon si nse eto bi nwon o ti se ma pa awon eja inu omi tutu.

Nwon ti bere si se awon odo nibiti nwon o gbe ri eja omi tutu pa. Ijoba si nse iranlowo fun won.

# Ogbeni Lijadu Lo Fun Ilosiwaju Eko



Enia dudu ti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni Yemi Lijadu, ti o je okan ninu awon ti o nse ikede ninu ero asoro-magbesi ni o mba Dr. Tyrone Guthrie I. D. soro yi.

Ogbeni Lijadu lo ma ndahun ogun ibere (twenty questions) ninu ero asoro magbesi nigbati o mbe ni ile Nigeria.

## OLOPA TO GB'OWO-EHIN LUGBADI

ENUGU. Ariwo ekun awon ebi omokunrin olopa kan ti nwon fi sun esun wipe o gb'owo-ehin lowo odaran kan, l'ogbojikan ni Kotu nigbati adajo sakonko ewon osu mejidinlogun mo lara.

Irohin ti a gbo ni wipe, olopa na je oga onipo kini (First Class) sugbon o se kanle wipe iro ni nwon pa mo on, o si so wipe idajo na ko te on lorun, nitorina, on yio gbe ejo na lo si Kotu arotuuro.

## IBERE NINU ILE IGBIMO NLA

EKO. Okan ninu awon olugbimo (House of Representatives) lo bere wipe, ki Olotu ilera ilu so fun won, kini ohun ti Atom Bombu yio da sile nipa alafia awon enia bi nwon ba yin etu oloro na ninu okun yanrin ti Sahara?

Olola Ayo Rosiji, Olotu ilera ni Eko dahun wipe, on ko ri i ri, on ko si ko eko nipa re ri, eyi ko jeki on le so. Bi a ba si wipe bayi ni ki a se tabi bakan ni a ntan ara wa je ni. Ohun ti awa ri pe o dara ni ona ti ijoba apapo ngba.

## OBA ILORIN NI ON KO FE EGBE SERAFU

ILORIN. Oba Ilorin, Malam Sulu Gambari pase ni afin re wipe on ko fe egbe Serafu mo nilu on, nitorina ki gbogbo awon omo egbe yi ko aasa won, ki nwon bo sehin odi.

Akowe egbe Serafu dahun wipe, ki awon to de Ilorin ni awon ti bere ase lodo Ajele, o si fun awon lesi wipe ayafi bi a ba le duro ni Ita Onimalu.

# Awon Oluko Lo Pade Iya Oba Nilu Oyinbo



**Adajo enia, lati orile-ede kọkan nigbogbo aiye lo peju sigboro ilu London fun ıgbimo kan ti nwon ṣe ni oṣu July lati jijọ ṣe ipinnu lati fi ẹgbẹrun enia kun awon ti a ti oko ni ẹko olofẹ**

Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni T. O. Ejiwumi Alabojuto awon ile Ẹkọ ni agbegbe Iwọ-orun, Nigeria, ti o mba Ọgbẹni Geoffrey Lloyd, Alabojuto ile ẹkọ tilu Oyinbo sọrọ nı Lancaster house.

## Oba Ilorin Fe Wuye

**ILỌRIN. A gbọ Irohin wipe Ijọba Ibilẹ Ilọrin ngbaradi lati se iwuye fun Ọba Ilọrın titun ti o sẹsẹ jẹ Malam Sulu Gambari A si gbọ wipe, Okowo.- din-lẹgbaa (£1,800) pọnun ni nwọn fẹ na fun ti iwuye ọba na lati ton Afin rẹ se. Ọjọ Iwuye na koiti si ninu ero.**

**Awọn enia meje ti nwọn yan lati lọ ro ọrọ na wa ni Malam Aliyu Baba Agba, Balogun Gambari, Malam Suberu, Mọgaji Arẹ, Malam Mohamodu, Wasiri Ilọrin, Cloye Arowolo Oyewọle,, Ọba Ilọfa, Malam Sedu Alao, Balẹ Bala, Ọgbẹni J.O. Daniel, Akapo owo Ijọba ati Ọgbẹni A.K. Ọba, Sẹkitẹri Ijọba ıbilẹ.**

## ENITO F'AGBARA MU IYAGBA W'EWON

AKURE. Okunrin kan ti ko ju omo odun meji lelogun lo pade iya arugbo lona oko, o ni iya na duro, lo ba ki mole, o si fi agbara ba lo po.

Koiti kuro lori iya agba na, ti awon enia fi ba won lenu re nwon si mu odomokunrin na lo si sobu awon olopa

Adajo so wipe, iru iwa ti gende odomokunrin yi hu buru tobe ge, ti o fi je pe ewon odun gbere ni ijiya re, ati pelu iru iwo odomode bayi, ni ijinji ojo aiye re, iwo ko ri eniti iwo yio ki mole, o wa je iya arugbo yi, elewu lori ti ojo aiye re ti le ni adorin odun.

Adajo na se anu fun ojo ori omo na o ni ki o lo si ewon odun mewa dipo odun gbere.

Kere o !

A ni orisirisi ogun German to sẹsẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos

## Eniti O Ngbawe Orire Se Jibiti

Ọkunrin kan, ti o ngba iwe Pools lowo gbogbo enia ati akowe rẹ kan, ni Ọlopa ramu ti nwon si gbe won janto dewaju adajọ fun ẹsun wipe, nwọn pade mowo bi £52. 14. 6, owo na je ti Ọgbeni Salu Olọrun-Nimbẹ ni Ijebu Ode. Awon mejeji so wipe awon ko jebi. Adajo ye ẹjo na si Friday 4th oṣu September 1959.

## OKUNRIN AGBE KAN SA ABURO RẸ PA

ADO EKITI. Ọkunrin agbe kan ti o ṣe ode lo sinu igbe, ri ohun kan ti o fi ara jo Oro ile, tabi eranko ni okunrin agbe na ba rin sunmo o si ṣaa ni ada lehin ti o ti saa ni asapa tan, lehin na ni oju agbe na wa mo kadara ti o si ri wipe, aburo re lo ti nsa ni ada latigba yi wa.

Eyi ni ẹjọ ti ọkunrin agbẹ na ro niwaju Adajọ. O tun sọ bayi kun oro re wipe Aburo mi ni, mo tile feran re jọjọ.

Ibe ni Adajọ gbe jsa ni koro wipe o to, iregbe ti o wi ti to bi o ba je wipe lotitọ ni iwo feran re, ki re tun ku erikan niwaju adajo ọdaran ninu kotu Ganran nibe ni iwo yio ti rohin fun gegebi iwo ti feran re to.

Adajo kekere na ro oro agbe na titi lo ba fi oro ejo re ranṣe si kotu odaran na (Assizes). Nwon si mbe lenu oro yi, bi a ba si ti tun gbo nipa re si ao jeki e gbo.

## JAMANI FẸ BA NIGERIA GBA BỌLU

Nigbati ina Eko njo geregere ninu ere Football gboju gbaiya lọ ta awon Gesi laiya lati ba won f'aya-lu aya gba bolu.

Ni wara nsesa ti nwon gunle si ilu Liverpool, ti nwon bere ere, mokanla ni nwon na awọn ara ilu na. Bi o tile je wipe awon osere ile Nigeria ko tun ri aye miran mọ lati ṣe be, sibe nwon gbidanwo niba ti won.

Lodun 1959 ni awon elere bolu ti Gesi tile-tona wa ba Nigeria ta pero nwon na wa tinu-tehin. Eyi tile dun so, a le so pe, iya ti Nigeria fi je ilu Liverpool ni nwon gbesan. Eyi si dun be.

Ṣugbon koto ki a gbo wipe awon Jamani ti o mbo wa ba Nigeria ta pero ninu ere football ninu osu August, tun bori enia dudu.

Nitorina, o di owo nyin o ẹnyin elere bọlu Nigeria.

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFẸ LAGOS"
P. O Box 407 Phone 23370

VOL. XI. NO. 636. SATURDAY AUG. 8 - AUG. 14, 1959


# T'Olorun Ko Ja...

"Ọmọ araiye lo gun", ni ede ti a le lo lori igbesi aiye ọmọ enia l'ode aiye wa yi. Nitoripe, ko si nkan ti enia le ṣe ni aṣeyanri si rere l'ode aiye yi ayafi bi awọn ọmọ araiye, ti awọn Musulumi npe lọmọ Anọbi Adamo ko ba na owo aidara si nkan na.

Ko si eniti Ọlorun ko ṣe fun, ṣugbọn awọn enia ti ko ni jẹki t'enia sunwọn nkọ? Eyi na ni awọn Yoruba ṣe nsọ wipe "Ogun ni ile aiye yi" Olukuluku enia si ni lati mura giri lati ja ogun na ki oluwarẹ le lo iba igba ti Ẹlẹda pese silẹ fun u pẹlu igbadun.

Pataki julọ, iwa olukuluku enia ni yio ṣe elegbe ẹhin rẹ, nitoripe awọn Yoruba mọni-mọni ti pal'owe wipe. "Enia ma jẹki t'enia sunwọn, tẹni to ma sunwọn ko ni gbọ" iyẹn nipe, oluwarẹ nilati ṣọ iwa ati iṣẹ rẹ si Olodumare ati si enia ẹlẹgbẹ rẹ ni rere. Nitorina "onilabu nile aiye, ti ẹ ntọ ẹ lẹhin" ti oluku-luku enia ni yio ma tọ lẹhin.

Ẹ ṢỌRA.




# Olotu Ijoba Gesi



ỌGBẸNI HAROLD MACMLLAN

Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni awọn igbimo ilu Oyinbo bere lọwọ rẹ, bi o ba gbọ nipa ẹtu Oloro ti awọn Faranse fẹ ju sinu okun Yanrin Sahara. O dahun pe bẹni, on ti gbọ. Ko nṣe ẹtu oloro ti H. Bombu ni nwọn fẹ ju, eyiti nwọn fẹ ju ko lewu rara.

## WOLI TI O PE ARA RẸ NI GUDASI DE

YABA. Ọkunrin Egun kan ti ko gbọ ede Yoruba rara, lo wọ aṣọ adura pupa, o di amure pupa, o mu ọpa tẹrẹ kan ti o jẹ idẹ dani, o si mu agogo adura dani, o nkorin o si njo on pelu omokunrin kekere kan.

O sọ wipe eti awon kun pupọ fun iro ti awon ngbọ nipa orisirisi Jesu ti a ngbọ iro re pe nwon wa nilẹ Nigeria Gegebi Jesu Agege, Jesu Oyingbo, Jesu Ijebu-Ode ati Jesu Kalaba.

Eyi ni akokọ jade on, ohun ti on jade fun ni wipe ki on wa fi ododo Jesu Nasarẹth han ki on ri pe gbogbo awon Jesu na ni a kan mọ agbelebu, ki on to pada si ilu on ni Abomi-Kalafi.

Bi o ba di ọjọ Sunday 9th August 1959, ni on yio lọ ṣe wasu ni Oyingbo, boya Jesu Oyingbo yio jade si on, nigbana ni on yio fi ami ti on han gẹgẹbi Gudasi on a si wipe ki o mu otitọ ọrọ tirẹ jade, o daju pe oju yio ti i.

Lehin na ni ngo lọ ba Jesu Agege ati awon yoku.

## INA JO NI OKUN, ILE MẸJỌ RASU

Lọjọ keta oṣu August 1959, ni ina nla kan jo lọna Okun ni abule Ọkọya, ile mẹjọ lo si jona raurau.

A gbọ wipe ohun to fa ina na ni pe awon ọmọde kekeke lo din ẹja, lojiji ni epo gbina, ina si ran mọ ara ọpa ti nwon fi kọle.

Nigbati awon Panapana de nwon ri bale ile na, ti o nda omi sinu ina na, ti o si nlagun bẹrẹ, ṣugbọn awon obinrin ile na lọ pawọ rọ lokere ti nwon nworan.

Gẹrẹ ti awon Panapana de ni nwon pa ina na. Fun ile mẹjọ ti o jona na iwon ọgọrun enia lo di alairi le gbe.

## Itan Afese Pa meje

(Apa 9)
Lati Owọ Arokin

Nigbati Afẹsẹ pa meje pari iṣẹ iṣoro kẹta oba ṣe ikede ọjọ igbeyawo. Awọn onijo njo, onilu lu, alase nṣe, ọloti mu, iyawo na mirmgidin. Nwọn nawo, nọra.

Ko si ẹnit o mo wipe iṣẹ Tailor ni Afẹsẹ pa meje kọ, omoba ilu kan ni gbogbo enia npe. Nwọn se igbeyawo na tan, nwon fa iyawo lọ fun ọkọ.

Gẹgebi Afẹsẹ pa meje ti jẹ enia ti o ma nṣe ironran loju orun bayi pe. "Ehẹn! lati oni ti mo ti sokoto yi fun o iwo koiti pari rẹ, tabi iru ọrọ ba wonni lo ma nsọ bi o ba sun lọ.

Iyawo rẹ ko si fẹ ariwo bi o ba sun, iru oro siso bayi ko njẹki iyawo rẹ sun. Nigbati o ṣe, ọmoba yi mu ẹjọ yi lọ han baba rẹ. Baba na si pinnu lati yan awọn alagbara lati ji gbe lọ ki nwọn si pa dunu.

Lojo ti oba pẹlu omo rẹ ṣe ipinnu yi ni Afẹsẹ pa meje sọ fun ọba pe lọla ni on lọ silu on. Ọba tete yara pe awọn enia lati lọ ji Afẹṣẹ pa meje gbe lo pa.

Ni oru ọjọ na, bi awon ti oba ran lati waji gbe ti de ti nwon npa koro lati wole, beni Afẹse pa meje tun bere si ṣe iranran, o nwipe Ha! e de ba mi mu ida mi, nwon tun de. Nigbati awon ti oba ran ni ise ti gboro yi, o di bi o ko lo yago fun mi. Nigbati ile mo ni Afẹse pa meje ba mu iyawo rẹ kori silu re.

Eyi ni opin itan Afese-pa-meje.

## T' iya -t'omo Sonu Ni Ile-Ife

ILE-IFẸ Obinrin kan ti o njẹ Oyebade ati ọmọ ọwọ rẹ ti o njẹ Oluwaṣina, ti nwon ngbe agbole Olugbode ni Ile—Ifẹ ni a gbọ wipe awon mejeji sonu lọsẹ ti o kọja.

Johnson Oyebade ti o jẹ ọkọ obinrin ti o sọnu na sọ fun awọn ọlọpa wipe iyawo on sọ wipe, on la ala kan loju ala na nwọn sọ fun on pe aya ṣebi awọn ba fi ọmọ awon rubọ bi bi bẹkọ awon ko ni ṣe anfani laiye.

Lẹhin na ni on lo silu Edunabọn a yafi igbati on pada dele ti on si ba gbogbo ile ti o sofo. Nigbati awon Ọlopa tun lo bere oro lodo Oyebade o dahun pe on ko le so yala omo on ti ku tabi o si mbe laye.

Awon olopa si nwadi oro na si iwaju. Titi di bi a ti nwi yi, a koiti gbọ pe nwon ri oku tabi aye ti'ya-t'omo na.



AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.

# Odomobinrin To Nsere Jangiroba



Ob'nrin ti a nwo aworan yi ẹ okan ninu awon oṣere nilu Oyinbo on lo so okun mo ara eka igi loke ti o si bere si mi dire-diro, o nṣe ere jangiroba, gẹgẹbi eyiti igbimo Town Council Eko se sibi iṣere fun awon omode.

## OWO TE OLE TO FE JI MOTO GBE

EKO Oro ko dun nigba ti awon olopa di okunrin igiripa kan mu ti gbogbo awon omode ati agbalagba nkorin bayi fun wipe.

Oju ole re, Ole! Owo olowo
Ole! Aso alaso, Ole!

ti nwon si mu kori si iso olopa ni opopo Broad Street.

Kini okunrin na se gan?

Ohun ti a gbo wipe okunrin na se ni wipe, nigbati o de idi moto, ti o wo otun, wo osi lo ba ko sinu moto Opel na, o si awa ona lati si ọko na ki o gbe salo, sugbon okunrin kan ri i, lo ba ki gbe ole.

Sugbon okunrin na kalo, o si je gbogbo enia ko le wo o jade, ni awon ba ke si 999. A yafi nigbati awon olopa na de ni nwon to le wa igiripa na jade.

## Ẹ MA KA IWE IROHIN ELETI-OFẸ LOSOSE O KUN FUN IROHIN ALADUN

## Eni Meta Ja Lori Tani Ya 'Oro' Julo ?

(Lati owọ Arọkin)

Ẹṣin. Ewure ati Adię mba ara won jiyan lọjọ kan, Ẹṣin sọ wipe awa ti a je eran ile, yatọ pupọ si awon eranko, eyiti o si y Oro gẹgẹbi ti emi esin ko s emi ni mo ni ala ti mo si la gbara ju ninu gbogbo eran ile, nitorina emi lo yẹ ki gbogbo eran ile ma gbọrọ si lenu.

Ewure dahun wipe, bi o ba je pe, iwọ ki iṣe agbalagba ni, mbe so wipe, e ponn die. Niti emi, Oro ti nyin ko ju ti emi lọ, ibe ni Adię ti dahun. pe ninu nyin ko si emiti o yo Oro bi emi Okoko; edekoyede bẹ si arin won, nwon gbo ara won lẹnu, to be ti o dija, ija na si po gidigidi ti gbogbo awon eran ile fi la ija na ti ariwo si nṣe gee.

Irohin ija yi de eti Ọbatala o si gbera lati wa pari edekoyede na fun won. Nigbati o de enikini rojọ, ekeji ro,tati enikẹta pẹlu. Obatala so fun won pe, ki gbogbo awon 'eran ile pejọ, Adie, Tolotolo, Awo, Pepẹiyẹ, Ogongo, Ologbo Aja Ẹṣin Malu, Ewurẹ, Agutan ati awon eranko bawonni, loju gbogbo won pe

Ọbatala wipe nisisiyi, ao mo eni ti o ju ara won lọ ninu awon metẹta. Ki eṣin kọkọ lọ pe Ọrọ kan wa fun wa. Inu gbogbo awon eran ile dun nitori pupọ ninu won ko ri Oro ri, nwon si fẹ lati mo. Ẹṣin bọ soju ọna, bi o ti nlọ o pade Ọrọ kan ti a npe ni Onile, nibiti o gbe joko si ni Ikorita, o wipe Ọrọ yi o jowo dide ba mi kalọ o jare, Ọrọ kanna sa ni gbogbo wa. O yo Ọrọ na lẹnu lati gbọ bẹ. O bere lọwọ esin pe, jọwọ duro fi han mi bawo ni ọrọ tirẹ tiri ?

Ẹṣin na dahun pe Ọrọ temi ni wipe, bi mo ba bimọ loni, oni kanna ni yio ma sare. Ọrọ na wipe ṣi ọ ! Ọrọ ni a ha npe eleyini, ṣa kuro ni waju mi, ki ma ba kọja lọ lara re. Ni Ẹṣin ba pada sile pẹlu itiju.

Nigbati Ẹṣin dele, Ọbatala ya kuro loju ọna fun u boya Ọrọ mba bọ lehin re. O bere wipe Ọrọ na ha da? Ẹṣin dahun pe o ni on ko wa. Ọbatala dahun pe, ko tan na, o ki iṣe Ọrọ : nj Ewure ba be si ta, o nwa Ọrọ lọ. Ẹ ma ka Iwe Irohin Ele-ọfẹ.

## Ijoba Franse Gba Sardauna Sokoto L'alejo



PARIS. Lasiko ti Sir Amadu Bello ti o jẹ Sardauna Ṣokoto ati Ọba Kano lọ si ilẹ Faranse a gbọ wipe Ijọba Faranse gba awọn mejeji ni alejo nwọn si ṣe ase rẹpẹtẹ lati fi yẹ wọn si.

Nigbati Sardauna mba Ijọba Faranse sọrọ, o fi ẹnu kan ẹtu Oloro ti nwọn fẹ ju si arin Okun yanrin Sahara. O sọ pe, ẹru mba awa ara ilẹ Nigeria nipa ẹtu Oloro na.

Nwọn si fesi dahun wipe otitọ ni ọrọ na, ṣugbọn ko si ewu kan nipa juju ẹtu oloro na. Pẹlupẹlu, apa ibiti nwọn gbe fẹ ju ẹtu oloro na si jinna pupọ silẹ Nigeria ju ilẹ Faranse lọ.

E.D. Ti ọmọ ma ku, ti ọmọ ma ye, a ni lati ki ọlọmọ ku ewu: ki enia na ibọn si eni tani le sọ pe ki o yin i nigbati ko mọ, ti ko si le sọ bi ẹtu wa ninu rẹ tabi kosi.

## Itan Awon Omoba Meje

Nigbati ọkọ wọn gunlẹ si odikeji odo, Akanbi bọ silẹ, eyi abigbẹhin ninu awọn ọmọba na duro, o si nwo ẹhin wo boya ọkọ miran ti mbọ, awon ẹgbọn rẹ kesi pe ki o kalọ tabi tani o nwo ? abigbẹhin dahun pe ara lo nfun on ko ma ba jẹ pe, ọkunrin na mbọ lẹhin wọn. Awọn ẹgbọn rẹ jagbe mọ wipe jọwọ kalọ o jare.

Bi nwọn ti ṣilẹkun ibi ere na, gbogbo awọn onijo na da muso fun awọn ọmọba na ni nwọn ba bẹrẹ ijo. Nibiti nwọn gbe njo ni Akanbi gbe ife wura ati ife fadaka o tẹ bọ apo. Nigbati agogo mẹta lu ti nwọn mbọ wa sile inu ọkọ ti aburo ni Akanbi wọ.

Ọlọkọ na sọ wipe ọkọ yi ma wiwo ju lọtẹ yi o, ọmọba na si dahun pe, boya ọti ti awọn mu pupọ lo faa. Nigbara ti ọkọ wọn gunlẹ, Akanbi sare o dile' o gun oke jade kuro ni Aja'lẹ, o delẹ o fi awọn nkan ti o mu pamọ, o bo sori busun rẹ o nhanrun.

Nigbati awọn ọmọba dele Akanbi ni nwọn kọkọ lọ wo, nwọn si ba lori ibusun rẹ inu won dun, nwon ko bata won ati aṣo won pamo, nwon si lo sun.

Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ. Lọsẹ ti o mbo ẹo gbọ nigbati Akanbi ntu aṣiri awọn omoba mejeje ti o si nfi ẹri ti i nidi.

E MA KA

IWE IROHIN

ELETI-OFE

LỌSỌSẸ

O KUN FUN

IROHIN ALADUN

## ỌKUNRIN KAN ṢA IYAWO ẸGBỌN RẸ PA

AKURẸ. Ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Michael Oni Olola fi ẹnu ra rẹ rojọ ninu Kotu Ọdaran (Assize) wipe, nigbati o di ọjọ keje ti on ti jẹ ọbẹ ila abami kan, ni nkan na tanna si on loju, ni on fa ada yọ ti on si ṣa iyawo 'arakunrin on ti o loyun sinu pa.

On gbagbọ wipe, ọbẹ ila ti on jẹ yẹn ni egbogi kan ti o le ma ti e n i a lati pa ẹnikẹni nigbakigba ti a d a ba ti wa nitosi oluwarẹ wa ninu ọbẹ na. Adajọ ni ki nwọn lọ yẹgi fun ọkunrin na.

Ọkunrin keji ti nwọn mu pẹlu rẹ ni Adesanmi Abẹrẹoje ẹsun tirẹ yatọ diẹ ninu oṣu September ọdun to kọja nilu Ondo Abẹrẹoje jẹun yo tan, o fa ada yọ, o si ṣa iyawo rẹ pa ku patapata. Adajọ ni ki nwọn lọ yẹgi fun ọdaran na.

## ẸNI TO NṢE ỌTI BỌLUGI FARA GBALAMỌ

ABẸOKUTA. Ọmọkunrin agbẹ kan ni awọn ọlọpa ka ọti Bọlugi mọ lọwọ ti nwọn si gbe lọ si waju Adajọ

Adajọ bere lọwọ ọdaran na wipe iṣẹ kini o nṣe, o dahun, o sọ f u n adajọ wipe, emi ko jẹ purọ niripe mo ti bura pe n k o ni purọ. Iṣẹ m e j i ni mo nṣe. Mo nṣe agbẹ, mo si tun mọ ọti Bọlugi nişişe ju awọn ẹlẹgbẹ mi lọ.

Nigbana ni adajọ dahun pe "Nitoriti iwọ mọ ọti bọlugi ni şişe tobẹ ti ko si ẹniti o mọ ọ se to ọ, ki o yara lo san adọta Pọnun bi bẹkọ ki o lọ si ẹwọn oşu mẹfa

## Agbepoo Ri Oku Omo Ninu Pokiti Nilu Aba

A B A Ọkunrin agbepoo kan lo ma ẹjọ wa sun lọdọ awọn Ọlọpa wipe nigbati on nda Pokiti ile ti o wa ni No. 199, Cameron Road, ibẹ ni on ti ri oku ọmọ ekee ninu igbe.

Ọlọpa si ranşẹ pe gbogbo awon ti o ngbe ile na, awon bere pe tani şeşẹ bimọ ti o je ara ile na? nwon ko si ri ẹniti o le sọ. Awọn ọlọpa gbe oku ọmọ na lọ sile Alaisan fun ayẹwo.

Awọn ọlọpa sọ wipe, ara fu awon fun iru iku ti ọmọ na ku. ko ma se jẹ wipe ọdaran obirin lo fi ọwọ di ọmọ na ni imu pa tabi ki o fi ọwọ tẹ ni ọna ọfun pa lẹhin ti o bi ọmọ na tan. Awon ọlọpa si nwadi ọrọ na siwaju.

## EGUNGUN KAN WỌ ẸWỌN NI IBADAN

IBADAN. Okunrin alagba kan ti o njẹ L a s u p ẹ ti o ngbe Egungun, ni awọn ọlọpa ra mu ti wọn si gbe duro niwaju kota ibilẹ nilu Ibadan.

Ẹ sun ti nwọn f i sun gungun na ni wipe o huwa ti o lodi si ofin ti o s le ba alafia ilu jẹ, o ba awon enia ja o si nfi a d a dẹruba e n i a.

Adajọ ri wipe Egungun na jẹbi nitoriti nwọn mọ pe bẹni o ma nşe nitotọ Adajọ ni ki o lọ san Pọun marundilọgọrin, tabi ki o lọ si ẹwọn oşu mẹfa.

Awọn Ọlọpa sọ fun ada jọ pe aşana ti di iwa ọdaran yi nigbati nwọn ba ti dajọ egungun ni ọdaran yio ma şe kuku-kẹkẹ.

A gbọ pe Egungun na bẹbẹ pe ki adajọ fi ori ji on.




## Ogbeni Sowole Di Alaga Igbimo Ilosiwaju Ise Ilu

Ọgbẹni M.S. Şowọle ti o ti figba kan jẹ Asoju fun ilẹ Nigeria ni ilu Oyinbo, labẹ Ijọba Iwọ orun ni a gbọ wipe o ti koro ni iru ipo bẹ, awọn si ti yan si ipo Alaga igbimọ Ilọsiwaju işẹ ilu, eyiti Ijọba Iwọ orun ngbero lati da silẹ laipẹ.

A si tun gbọ ir hin kan lati ọdọ Ijọba na wa wipe, ẹniti awọn yan fi yio rọpo Oloye Şowọle ni L ọ y a Akintoye Coker ti yio ma ba işẹ Asoju lo fun Ijọba Iwo-Orun nilu oyinbo titi ti iwe ndran yio tun fi jade.

Ẹ MA KA IWE IROHIN
ELETI-OFE
LỌSỌSẸ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

## Bassy Sa Pe Agbara On Ju Ti Inaki Lo



LOS ANGELES. Ogbẹni Hogan Bassey, Olori awon Abẹṣẹ-kun-bi-ojo, ti o ti ilu Oyinbo lọ ji ẹlẹ nilẹ Amerika so wipe, nisisiyi, on gbagbo wipe on yio bori Davey Moore.

O soro yi ni apeje kan ti awon Oniwe Irohin pe fun u o wipe nisisiyi, egungun mi le bi igbati mo koko wa si ihin lati wa ba Davey Moore ja, agbara mi ti jide, o si dami loju pe lagi-lagi yio la lara rẹ lọtẹyi.

Fun gbogbo ọsẹ ti o ku Bassey yio ma ba wọn se idanrawo.

## IKU YẸ LORI ODARAN TO PA'NIA.

AKURE. Ọkunrin ti o njẹ Adetunji Jẹgede ni awon ọlọpa ranu fun esun pe o pa Ọkunrin kan ti o je ore iyawo rẹ, o si ṣa iyawo rẹ paapa lọgbẹ, ni awon ọlọpa gbe ni ejonto de kota nla (Assize).

Ọkunrin odaran apania na dahun pe, eni kodede ṣa ọkunrin na pa, idi rẹ ni wipe, ọkunrin ti o njẹ Fadora Ọlagunju na ndaba lati gba iyawo mi, Ọkunrin na ati iyawo mi, bẹrẹ si korin owe mọ mi, iyawo na nkọrin bu mi, o npe Fadora ni ọko on, eyi lo jẹki inu bimi jojo ti mo fi ṣa awon mejeji lọgbẹ.

Adajọ gba wipe nitoto ni nwon korin owe mo Jẹgede, o ro ọrọ na siwa sẹhin o ri wipe ibinu ni o mu Jẹgede ṣiwa hu, o yi esun rẹ pada si pe enia sesi ti ọwọ rẹ ku. O fi si ẹwon ọdun mẹtala.

## OLE TO JI MỌTO FI NWA ẸLẸWỌN SALỌ.

Ọkunrin kan ti o sa kuro ni ọgba ewon, wọ moto kan ti nwon jigbe, eniti o nwa moto na ni ole ti o ji moto na. Awon ọlọpa si ti nwa awon odolugbeku mejeji na ki ọwọ ọlọpa to tẹ won ni Ilorin.

Nigbati ọwọ tẹ awon mejeji na, nwon da eyi ẹlẹwon pada si Eko lati ma ba ẹwon re niṣo ṣugbon nwon ki ole ti o ji moto mole, nwon fi si itimọle, nwon wa nse iwadi ọrọ re lọwọ.

## Olotu Ijoba Ila-Orun Mbọ Wa'le



**Dokita Azikiwe ti a nwo aworan re yi ni a gbo wipe o ti woko oju omi nla ti nwọn npe ni "Apapa"** **nilu Oyinbo, o si npada bọ wa'le. Dokita Azikiwe pẹlu awọn isọngbe rẹ meji ni nwọn jijọ wọkọ na kuro nilu Oyinbo lọjọ Alamisi ọsẹ yi**

## IJỌBA NKO AWỌN OBINRIN TI KO LỌKỌ

KANO. Aboyun ati abiyamo ti o ntomo lowo pẹlu awon obinrin bi ogọrun ti awon ọlọpa ibilẹ ragabu nilu Kano lojo Tuesday gẹgẹbi iṣẹ wọn lati fọ ilu Kano mo fun iwa ẹgbin awon alarinjẹ obinrin.

Nwon bere iṣẹ yi nikan bi ọsẹ meji sẹhin, nwon si ti ri ko to irinwo obinrin nisisiyi.




## Awon Ti O Je Orire !!

Ninu orire ti Ọlọla T. O, S. Benson M. H. R. fi inurere re gba ipe wa lati ba wa se Alabojuto rẹ ni owurọ ọjọ Monday, ọjọ keta osu August, 1959, awọn nọmba to s'orire jẹ ninu ẸBUN OFẸ ti a fun wọn ninu OSẸ ORIRE na nwọnyi :-

| | | |
|---|---|---|
| No. | 5961 | Je ero Telefunken Television Set |
| ,, | 00067 | Jẹ Iwe owo Pọnun mewa. Iyẹn nipe oluware ni aṣẹ lati ra ọja oni pọnun mẹwa ninu Ile Itaja wa lọfẹ. |
| ,, | 01090 | Jẹ Aṣọ obinrin oluware yio mu eyiti o ba mu. |
| ,, | 00372 | Jẹ ẹbun igo ọti Champagne mẹta |

Ki ẹnikẹni ti iwe rẹ ba jẹ nomba wọnyi mu iwe na wa fi gba ebun-ofe ti rẹ.

M.B.T
(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T. dé, òkùnrùn ṣ̀ lọ. Ẹjẹ dúdú sárá oyi pọsẹsẹ. Àlá búburú wọ́ gbọ̀. àilèsùn r'ẹhin-ẹkùn. M.B.T. ṣ'ogùn ẹjẹ ti nmú ni jẹun bi'kan, amú ni yàgbẹ́ bi òkùn, amú ni tọ̀ bi òkòtó. Abiwẹ́rẹ́ f'ẹ́boyún, agbèjẹdi pawon abiyamọ. Ẹhin-dídùn, ẹsẹ-wíwú ati àiya-jíjá ko si pẹ́niti nio o.
4/6d pẹlu 1/6d owó-ọkọ̀.
ARADAN STORES P.O.Box?
EBUTE-METTA.

FUN OJA TO GBADUN BHOJSONS

BHOJSONS OYINGBO, P. O. BOX 63, EBUTE-METTA

Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28 Kosọkọ Street P.O. Box 467 Lagos, Phone 23370